**Akiyesi**

Imoran fun awon omo Ajase-Ipo lati owo awon omo egbe Aiye Mojuba Ajase Ipo ti bere si jade ninu iwe Irohin Imole lati ibere Odun yi lagbara Olorun

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**Oja kota ?**

E ma polowo Oja yin sinu Iwe-Irohin - "Imole"

VOL. IV No. 188 MONDAY JANUARY 2 — JANUARY 8 1961 KOBO KAN (1d)


# Nwon ni ki a ko Iwe, a ko iwe pari sugbon ko si ise

EKO:- Nwon ko wa wipe, ki a ko awon Omo wa ni eko iwe titi de iwe Kefa, lehin na awon Omo ti ko ba le te SIWAJU NINU EKO MỌ, KI NWON LỌ BERE IṢẸ. A GBOPE OGIDINLEJE AWON OMO ILE EKO LO JADE KURO NI IWE KEFA L'ODUN TO KỌJA ṢUGBỌN TI NWỌN KO RI IṢẸ FI ṢE

Ogoji le ni ọdunrun (340) ni iye awọn ọmọ ile ekọ to jade lọ fi orukọ silẹ lọdọ awọn Alaṣẹ wipe nwọn nfẹ bẹrẹ iṣẹ lati ma ṣe, ṣugbọn enia mẹwa pere lo ri iṣẹ ṣe ninu won. Oga Olotu ti o nwa iṣẹ fun gbogbo enia sọ wipe, ni akoko yi ati ka iwe ko ja gegebi a ti ri iṣẹ ṣe. Nigba lailai, bi ọdun ba nlọ si ipari bayi nṣe ni awọn Oyinbo ma nṣe abẹlẹ ti a mbẹ Abiyamọ lọdọ awọn Olukọ ilewe, nitori ki nwọn le ri akọwe ti yio ba won ṣiṣẹ. Nigbati iwe kikọ lo ṣoro, ati ri iṣẹ ko ja. Gbọ bi Okunrin Olorin Eko kan ti ọ njẹ Bẹgbaji ti fi ọrọ iwe korin:— Eni bimọ ti ko mọwe, Ina jo tabi ko jo, Aimọwe njọmọ niya. Aiyele Baba, Aimọwe njọmọ niya.

Awọn ọmọ to fi ilewe silẹ nibẹrẹ odun 1960 ṣi ku enia mọkanle-lọgọta ti koitiri iṣẹ, ogunlọgọ wọn ni yio tun lọ fi oruko silẹ fun iṣẹ. Pataki ti o wa nibẹ ni wipe awọn Onisẹ ko ni fẹ lati gba awọn ọmọ ilewe nwọnyi, nitoripe, nwọn ni lati tun wọn kọ ni iṣẹ ti nwọn fẹ lati ma ṣe ni.(Apprenticeship)

Nipa awọn ọmọ ti o jade nilewe giga, Ọgbọn ni awọn to foruko silẹ, mẹtalelogoje lo tun ṣeṣẹ foruko silẹ fun iṣẹ ti nwọn si jade ni iwe Kesan ati ekẹwa. Aye mẹrinle-ladota lo ṣi silẹ fun awọn to kawe mẹwa, aye mejileladorun lo ṣi silẹ fun awọn to yege ninu Idanwo G.E.C.

## Faranse tun yin Etu Oloro ni Erekusu Sahara lerinketa, awon Egbe NEPU si gba Olotu Apapo Ile Naijiria ni imoran lati jawo ninu ajumosepo pelu Faranse

AGBO wipe awọn Egbẹ Oṣiṣẹ ti o wa labẹ akoso Ogbẹni Imoudu kesi Olotu Apapọ Ile Naijiria, Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa wipe ki o tete pada si Eko, ki o din isimi rẹ ku eyiti o nṣe ni Ilẹ Ariwa nisisiyi lati le wa mojuto rogbodiyan ti Faranse da silẹ nipa yiyin etu Oloro rẹ ni Ilẹ Ariwa Sahara lori erinkẹta.

Ninu iwe ti awọn Egbẹ Oṣiṣẹ yi kọ si Ọlọla Abubakar ni Kaduna, wọn fihan Olotu wa na wipe yiyin ti awọn Faranse yin etu Oloro yi jẹwọ iwa ika ati ipania ti o wa ninu Faranse, eyiti Ijọba nilati tete mogiri si kiakia

Awọn Egbẹ Oṣiṣẹ tun dahun wipe iwa ojo ti Ijọba Apapọ Ilẹ Naijiria nhu ko tẹ awọn lorun nipa aitete mu ileri ti Igbimọ Apapọ Ilẹ Naijiria ṣe laipẹ yi ṣẹ.

A sọ fun wa wipe awọn Enia Ilu yi ti fun Ijọba Ilẹ Naijiria ni aṣẹ wipe a ki imọ Ijọba Faranse tun le yin etu Oloro won wipe ti won ba ṣe bẹ ki Ijọba gba gbogbo ohun ini wọn ti o wa ni ilẹ wa, ki a ma si ṣe ba wọn ṣe asepọ mọ. Ni Kaduna papa awọn Igbimọ Egbẹ N. P. C. na tun ṣe ipade pajawiri ninu ninu eyiti Olotu Apapọ Ilẹ Naijiria papa ba wọn joko ṣe ipade, ipade na papa si tun fi imọ ṣọkan sọ fun Ọlọla Abubakar wipe ki o da gbogbo ajumọṣepọ awọn pẹlu Faranse duro kiakia.

Awọn Egbẹ N.P.C. tun kesi gbogbo awọn Orilẹ Enia dudu wipe o yẹ ki gbogbo wa fihan Faranse wipe ko si bi agbara ohun Oṣẹ won tile po to ki o le to agbara ero inu enia. Awọn Egbẹ NEPU ni Kano papa na tun ṣe ipade bakanna wọn si sọ fun Ijọba wipe ki wọn jawọ ninu ajumọṣepọ pẹlu Faranse. Bakanna tun ni Dokita Okpara ti iṣe Olotu Ilẹ Ila-Orun tun sọrọ jade wipe lati Oṣu Kerin Ọdun ti o koja yi ti awọn Faranse ti yin Etu Oloro wọn, ni awọn ye ṣe owo pọ pẹlu wọn, awọn si wa nda ni aba nisisiyi wipe ki Ijọba Apapọ tete mogiri si ọrọ na.

Dokita Okpara tun so wipe nigbati a gba Ominira awon ge ọwọ ẹtọ diẹ, lati fihan orilẹ-Ede aiye wipe a ni ifẹ gbogbo enia, pẹlu ero wipe awọn Faranse ko tun ni jẹ da ni aba mọ lati tun yin ẹtu Oloro na.

Dokita Nkrumah ti iṣe Alakoso Ilẹ Ghana ge irin ajo rẹ ti o nrin lọ si Ivory Coast kuru lati pada si Accra fun ipade pajawiri ti o fẹ ba igbimọ rẹ ṣe lori, ni ale ana ni a ro wipe yio ba awọn Oṣelu ẹgbẹ rẹ sọrọ, Dọkita Nkrumah tun tun kẹsi awọn ti o ṣe alakoso ati Olotu agbegbe ilẹ Farase lati fihan ninu iwa wọn wipe iwa ti Faranse.

Alakoso ile Ghana na yio fo lo si Casablance ni ijọ Monday ọjọ kẹta osu January 1961 fun ipade pẹlu enia dudu voku, ninu ipade na ui a o ti Ọba Mohammed ti ilẹ Morroco, Alakoso Nassar ti ilẹ Arab.

Ṣugbọn ninu ipade yi Ilẹ Naijiria ko ni si ninu rẹ

EGBE Enin dudu kan ti a npe ni ICFTU ṣe ipade ni ọjọ Alamisi ti o koja yi won si fi ete ati abuku kan iwa abuku ati aibikita ti Faranse hu si enia dudu o tile kesi gbogbo enia dudu gbaruku won lati le da ibasọpọ pẹlu Faranse duro, ki wọn si fi ọwọ rin gbogbo ohun ini Franse, o tilẹ tun da laba wipe ki gbo gbo oṣiṣẹ to lọwọlọwọ lati le fi ilodisi wọn han.

# IMOLE

ESIN ORO WA-
IMOLE DE OKUNKUN
PARADA
Editorial Works & Office
16, Bamgbos Strt,
Lagos
Telephone- 21986
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street,
London W. 1
IVAN F. LUCKIN
6 LAURENCE Pountney
Cannon St. London. E.C. 4
U. S. A. Representative
REGIS BOBONIS
2528 MAMON ST.
PITTSBURGH PA.
U. S. A.


## Enyin Obi, e ko Omo nyin ni iwa to rewa to si dara

E ko awon omo nyin ni ona ti o dara, ti nwon lo nitoripe bi nwon ba dagba sinu re tan, ki nwon ma ba yi kuro ninu re. Solomon oba Israeli ti to ki o lo so wipe, omo ti o ba gbon, yio ma mu inu baba re dun, sugbon omo ti o ba go, inu iyare ni yio ma baje.

Oro wonyi ni a fe fi si enyin okawe Irohin Imole leti nipa awon omo nyin ti o nlo si ilewe. Owe yoruba kan so wipe owo ara eni lafi nko meje. Owo ara eni la si fi ntun iwa eni se.

Opo ninu awon omo ile eko ti o mbe lode ti oni, ni awon obi won ti ba iwa onje. Ohun ti o ye ti o si dara ni wipe ki awon obi ma deru ba omo won, ki nwon le ma sa fun iwa agbere ki nwon le gbajumo eko won.

Ko si omo kan ti o nfe fi ojuboro ko iwe ayafi bi awon obi re ba fi ipa mu lati ko iwe. Ko nse ohun oro fun awon omolewe lati ma lepa Obinrin kakiri Ni aiye igbani, bi obinrin tabi iya kan ba gbo wipe, nse ni omo re nlepa obinrin kakiri, nwon ti mo pe omo na fe di afori nuni, were ni won o ti so agbeje mo omo won nidi. Sugbon awon Obi ti o mba omo won lori je yio wipe, o fi won sile, o jare nitori igba won lo mbe lo de.

Okunrin g b a j u too kan wa nilu Eko, ti o je wipe obinrin lo so di olori buru ku titi di oni. Nigbati o nlo silo Iwe t'obinrin yio de onje mo inu igba nwon

si gbe lo fun nipa ilewe, oluko ba wi, nwon na a aiyebanwa amlanbo, ayafi igba ti nwon so di o l o r i bunuku gegebi oti iti loni. Enyin Obi, e mase gba ko omo nyin ma lepa obinrin tabi Okunrin nse lo mba enia lorije.

### AKIYESI

E wa ra Iwe Adura Odun titun ni Opopo 11, Denton Bridge Street, Tabi ni Opopo 21, Ondo Street, West. Ebute -- Metta. 6d. per Copy. Doz 2s 6d.

## Eku ewu Odun Titun

ENYIN Iya mi ati baba mi, mo ki yin lopolopo, e ku ewu odun titun ti a wo yi.

Enyin egbon mi lokunrin ati lobinrin ati enyin elegbe mi, omo ile eko



E. Adekunle Adeniji
Omo ile eko St. Peter's
(Faji) Lagos.

kakiri agbaiye e ku ewu odun titun, Oluwa jeki a se opo re. Siwaju si, mo ki gbogbo enyin olukawe Irohin Imole fun irawo yin losose ti e fi nra iwe Irohin na, Oluwa ko ni jeki apo yin gbe tara.

Mo si tun dupe pupo lowo baba to bi mi lomo ti o si tun fun mi laye lati ma kowe sinu iwe re na oloyinmomo, irufe iwe na ti mo nko nfun mi ni anfani lati ma lo siwaju dara dara ati lati ma ewo ohun ribiribi ti o nlo larin agbaiye, mo si tope yio je isiri fun awon odomode omo ile eko elegbe mi nipa kika orisirisi Irohin to ma nyo

WO IYOKU NI OJU EWE KARUN

## Imoran fun Omo Ajasse-Ipo

### Lati Owo:- Omo Egbe Aiye mojuba Lagos Branch

INU wa yio dun bi Olotu Iwe Imole bale gbawa lati ba gbogbo Omo Ilu Ajassepo so oro nipa Edekoyede ti o sele nigbagbogbo ninu Ilu Ajassepo. Eyi ni wipe awa Egbe ti o nba won soro yi je Olufenilowo ninu Ajassepo sugbon pataki julo ninu gbogbo oro ti a fe ba yin so afe ki e pe ara yin lati le se atunse gegebi ilosiwaju tise ma ba Ilu Ajassepo toripe ote Ajasse ti bere kose ojo kekere, akoko bere ote Ajasse, ori Olupo Arigan titi o fi de ori Olupo Arojo titi o fi tun de odo Olupo Orimadegun to wa lori Ite nisiyi, kini nyo wa lenu ? bikosepe awa ati wa lanso arawa leno. Awa Egbe yi fi eyi se alo fun gbogbo omo Ajassepo, tobaje pe Egbe Igbomina Parapo lo fe mase, ki o mase lo, tobasiepe Egbe N.P.C. Olomi lofe mase, ki o mase lo eyi komu ija dati tan, toripe awon Egbe gbogbo Ilu to wa laiye yi lonse Egbe Oselu toba wun won.

SUGBON anfani Ilu ati Ilosiwaju Ilu ni olukuluku nwa lodo Ijoba re, Bi ohun rere tise le ma wo Ilu Ajasse, on loye ki a ma wa abe yin pipopipo ki e jeki amu ti eta inu kuro ki e tun Ilu Ajassepo se. Eyi oto ofo fila Imale nku peke, E wo gbogbo Ilu to rogba yi waka, gbogbo won lonse egbe meji-meji, sugbon ilosiwaju ni won nwa fun ara won, ti egbe k a n ba ni agbara lati fa Ina sinu Ajasse ki egbe miran simu ara ati fa Omi wo ilu Ajassepo, ki olukuluku majowu ara won ki ohun rere oma wo ilu Nigbana Egbe kini ati keji yo wa ni itelorun, won adi ore arawon, e g b e ti oruko re wani oke iwe be yin gidigidi pe ti e bari nkan ti o le mu ilosiwaju ba ilu Ajassepo ti e fe se, a w a egbe yi duro lati se iranlowo ti Olorun ba fun wa ni agbara.

O di igbakan na ao tun ma ka siwaju ni OSE tonbo




## Awon Osise ti o nwa Kusa (Irin) ni Oke-oya ba Olopa ja

JOS. Irohin kan wa wipe, awọn Oṣiṣẹ ti o nwa irin Irin tutu eyiti nwọn npe ni Kusa ti mba awọn Ọlọpa fa ijọgbọn lati nkan bi ijarun lori ohun ti o ndun wọn lọkan pẹlu ọga wọn nitoripe ọga na ko fẹ san owo Mbanefo fun wọn (Mbanefo Award) o si tun kọ lati tun sakani ọdọ awọn oṣiṣẹ ṣe.

Ọgbẹni H. C. A. Ejiru ti iṣe Baba isalẹ fun awọn oṣiṣẹ na ṣe ikede wipe, a tilẹ nki i, a nsa a, ọga awọn oṣiṣẹ sọ pe, on ko mọ enití o kọ, awọn ọlọpa oẹwe ko si jẹki a mi on yi ko gbogbo awọn oṣiṣẹ na lọ si sodi lọ ka Ajẹlẹ agba mọ ile, ki nwọn si fi ọran ẹdun wọn han a. O sọ pe, on ko mọ ohun ti o kan ọlọpa ninu rẹ nigbati oniṣẹ ati awọn oṣiṣẹ mba ara wọn ta pero ohun lori ọrọ ede koyede ti o wa larin tọtun tosi wọn.

Awọn Oṣiṣẹ ko mu ohun ija kọkan dani bẹni ko si ohun ipalara kan ti wọn mu dani rara de ipo ti enia fi le fura si nwọn, awọn ọlọpa tẹ kondo bọ awọn oṣiṣẹ lara, nwọn si lu wọn ni ilukulu tobẹ ti nwọn fi lu oṣiṣẹ kan pa, ti awọn oṣiṣẹ mẹdogun si fi ara gbaramọ.

Awọn oṣiṣẹ ti o mbẹ ni ibudo Barakin ladi, ni buṣọ mẹdogun si ilu Jos da iṣẹ duro, nwọn si bẹrẹ si ṣe imẹlẹ iye awọn oṣiṣẹ ti o wa ni barakin ladi pọ to 1,875. Ninu ijaka-li ti awọn Oṣiṣẹ ti o nwa kusa kopelu awọn Ọlọpa ni Malam Meikẹrẹ ku si awọn yo ku ti o gbọgbẹ wa ninu ile Alaisan nisisiyi nilu Jos.


Advt. 174

## Postage Stamps: New Definitive Issue

It is announced that the postage stamps currently in use, which were first issued on the 1st September 1953, will be withdrawn from sale at the close of business on the 31st December, 1960. A new issue of the following denominations will be placed on sale on the 1st January 1961:-

1/2d 1d 11/2d 2d 3d 4d 6d 1/- 1/-3d 2/-6d 5s. 10s. £1.

The Independence Commemorative stamps will also be withdrawn from sale on the 31st December, 1960.

## Ministry of Communication Lagos

15th. December, 1960.





## Okunrin mu ewe Taba Igbo nilu Oyinbo, o si di ero Ewon

ILU OYINBO:- Ọmọkunrin kan ti o njẹ Agbuyi ara ilẹ Naijiria ti o nṣiṣẹ ninu ọkọ ero ti oju omi kan ti nwọn npe ni Kalaba, ni awọn ọlọpa ka mọ ibiti o gbe ti nmu ewe Taba buruku kan ti nwọn npe ni Igbo, nwọn ki i mọlẹ, nwọn si mu lọ si wa-Adajọ

Adajọ bere lọwọ rẹ pe, iru iṣẹ wo li o nṣe ninu ọkọ? o dahun wipe, iṣẹ Alagbafọ ni on nṣe ninu ọkọ ero M. V. Kalaba Adajọ na bere lọwọ rẹ wipe, ewo ni ṣiṣe o jẹbi tabi ko jẹbi, o si dahun pe rara! on ko jẹbi ibẹ ni Adajọ ba bere pe, kini ẹsun re? Awọn Ọlọpa sọ wipe, nigbati Agbuyi ba ọkọ oyinbo gunlẹ si Tilbury, awọn Onibode lọ yẹ gbọngan rẹ wo nwọn si ba nibiti o nmu Igbo lọwọ, nigbati o-orun rẹ yatọ si o-orun Siga, ni Onibode na sọfun pe, on lẹ ri ewe Taba ti o nmu yi.

E ro rẹ ni wipe, ofin ti ilu Oyinbo ko de ilẹ yi, o gbe agolo eyiti o mu ku, o fihan Onibode wipe on niyi, ewe taba ti nwọn nmu nilu on niyọn Nigbati Onibode na ri pe Igbo ni, o ranṣẹ pe ọlọpa Agbuyi sọ fun Adajọ wipe on ko mọ pe, nwọn ko gbọdọ mu Igbo nilu yi.

Adajọ dahun wipe, ọrọ wọn ko gbọdọ mu kọ ni eyiti o mba sọ, ṣugbọn, o mu ewe Taba ajeji wọ ilu Gẹẹsi lai ni iwe aṣẹ.

Lẹsẹkanna o yi ọrọ rẹ, o wipe ẹnikan loju ewe Taba Igbo na si on ni apo Adajọ ri wipe ọrọ rẹ ko danmọran ni Adajọ ba ni ki o lọ gbawa fun oṣu meji

## Awon Aro! Eyo

1. Hu-u-haha, esuru kuru Hu-u haha

1 Mo yọ fun ẹ, mo yọ fun ara mi, ku atigba hu-u haba 3. Emi Avoruru, emi Afaruru, emi Awọ bi ere jana, hu u hah - 4. Alẹlẹ we ma lẹ Okuncun ma kun Birimu birimu.

# Irohin Imole Calendar

## 16, Bamgbose Street Lagos. Phone:- 21985

**Public Holidays**

| | |
|---|---|
| New Year's Day | Jan 1 |
| Ramadan FastingDay | Feb 18 |
| Lalatul Quadri | Mar. 16 |
| Good Friday | March 31 |
| Easter Monday | April 2 |
| Independence day | October 1 |
| Eid-El-Kabir | May 27 |
| Bank Holiday | Aug 7 |
| Maolud Nabiyyu | Sept 3 |
| Christmas Day | December 25 |
| Boxing Day | December 26 |

## Adura Odun

Olọrun, ẹniti ipese Rẹ ki itase lai ṣe ilana ohun gbogbo li ọrun ati laiye; Awa nfi irẹlẹ bẹbẹ lọdọ Rẹ lati mu ohun gbogbo ti ipanilara kuro lọdọ wa ki o si fun wa li ohun wonni ti o ṣe anfani funwa ninu ọdun yi. ki O si sọ wa di alabapin iṣura Rẹ ọrun

Lọwọ iku ojiji, lọwọ ijamba Mọto, ati lọwọ aṣe iri, Oluwa rere gbawa ninu ọdun yi. Amin,

**New Moons**

| | |
|---|---|
| January | 16 |
| February | 15 |
| March | 16 |
| April | 15 |
| May | 14 |
| June | 13 |
| July | 12 |
| August | 11 |
| September | 10 |
| October | 9 |
| November | 8 |
| December | 8 |



Alhaji Tafawa Balewa
PRIME MINISTER OF FEDERATION OF NIGERIA

BARIKA DE SALLAH

## 1961 CALENDAR 1961

**January**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 |
| 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 |
| 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 |
| 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 | 28 |
| 29 | 30 | 31 | | | | |

**February**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | 1 | 2 | 3 | 4 |
| 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 |
| 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 |
| 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 |
| 26 | 27 | 28 | | | | |

**March**

| Sun | Tue | Mon | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | 1 | 2 | 3 | 4 |
| 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 |
| 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 |
| 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 |
| 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | 31 | |

**April**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | | 1 |
| 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 |
| 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 |
| 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 |
| 23/30 | 24 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 |

**May**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 |
| 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 |
| 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 |
| 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 |
| 28 | 29 | 30 | 31 | | | |

**June**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | 1 | 2 | 3 |
| 4 | 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 |
| 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 |
| 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 |
| 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | |

**July**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | | 1 |
| 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 |
| 6 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 |
| 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 |
| 23/30 | 24/31 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 |

**August**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
| 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 |
| 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 |
| 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 |
| 27 | 28 | 29 | 30 | 31 | | |

**September**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | 1 | 2 |
| 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 | 9 |
| 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 |
| 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 |
| 24 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 |

**October**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 |
| 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 |
| 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 |
| 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 | 28 |
| 29 | 30 | 31 | | | | |

**November**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | 1 | 2 | 3 | 4 |
| 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 |
| 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 |
| 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 |
| 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | | |

**December**

| Sun | Mon | Tue | Wed | Thu | Fri | Sat |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | | 1 |
| 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 |
| 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 |
| 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 |
| 23/30 | 24/31 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 |

## Advt. No. 182

The Public is reminded that since 1st October all goods including Postal Parcels, sent from Nigeria to the Southern Cameroons are subject to Customs examination on arrival and that considerable delay and difficulty may be experienced by the consignee if the following procedure is not observed.

**1. Postal Parcels**

The precise contents and value of each parcel must be accurately stated on a Customs Declaration Form affixed to the parcel. A copy invoice must accompany commercial consignments and should be attached to the outside of the parcel in an envelope marked **"Invoice".**

**2. FREIGHT**

Sets of invoices for consignments sent by Sea or Air freight should be sent to the consignee in sufficient time to allow for the advance preparation of custom documents.


## IWE SI OLOTU

MO Fi iwe mi yi ki enyin Egbe odo ti Ijo Apostel Church ti Bawe-hundo pe e ku iye-duu emi yio se opo re o. Pataki oro mi si nyin ninu odun yi ni pe gegebi ati bo odun yi sile ti a si gbe odun 1961 wo, e je ka gbe wo pelu iwa to pe, ka wa sumo Olorun ka wa sa fun awon ese nwonyi. Agbere, Ojukokoro Aini iteriba fun awon agbalagba, Pansaga ati Oti mimu pelu. E lo ye iwe Galatia ori Karun ese kini titi de opin re wo (Galatia 5, 1-26) Mo ki enyin Agba Ijo gegebi Daniel, Joseph, Emmanuel Abodun e ku odun Eyi ni odun kini lehin ti a gba Ominira ni ile Naijiria. Odun ni odun na ati odun iranti pelu Hallelu-ya Ope, iyin Ogo ni fun Oba na loke Orun.

E kun fun adura fun Ilu wa, ki ilu le gba Ominira gegebi ilu to ku o. Mo dupe lowo Olotu I ohin Imole, iwaju lopa ebiti ma nre si. Iwaju le o ma lo o.

EMI NI S. ASHOJU (Bawe-hundo- Ipokia Area.)

## AKA-RERIN

Awon Agbalagba meji mba ara won sere, ekini wifun ekeji wipe, ha! ore mi, ese ti mo de ile re lana ti nko ti rio nile? Enikeji dahun wipe bawo lo se lero pe emi yio wa nile nigbati o gbe ile mi ti o si de! Okunrin yi ko tete fura pe oro apara ni ore on nso, o fi Orisa Ogiyan bura wipe on de ile re lana. Okunrin keji dahun pe haba! iwo agbalagba lo npuro bayi Erin!

O BERE LATI OJU EWE KEJI

ninu idanwo nigbati nwon rar. Gbogbo enyin omo ile eko elegbe mi, mo kesi yin e ku isinmi, Oluwa koje ki isinmi na ni anfani fun wa. Gbogbo enyin ti e sikuna ninu idanwo yin ndun 1960 mo kesi yin e mase so ireti nu Oluwa yio ran yin lowo ninu odun 1961 sugbon mo fi iran yin leti wipe ti e ko ba fe tun kuna ninu odun 1961 ni kete ti e ba ti wole isinmi ni, e o bere ise yin ni asekara ki e mase se ise yin ni abo, ki e si mo daju pe ise abo ti e se l'odun 1960 lofa ikuna yin. Moki awon oluko wa pelu

## E ku Odun, e ku Iyedun!



Awo! Awo'! Awo!!; Olorun mbe lehin Onisuru. Emi Oloye Awolowo fi gbogbo aiya mi, gbogbo inu mi ati Agbara mi ki gbogbo enyin Oluka iwe Irohin Imole, ati ni pataki gbogbo awon Omo Egbe Olope, wipe E ku Odun, e ku iyedun Olorun ko fi ire Odun na kari wa Asevi se Amodun Amin.

## Julius Adeola Odeku (LL. B.)



COUNCILOR ODEKU:— Mo ki nyin, gbogbo enyin omo Iya mi, omo Ilu mi, enyin omo egbe Afenifere, ati enyin omo egbe Odudewa wipe, eku edun, eku iyedun ki Olorun O a je ki odun yi je odun fun gbogbo wa. Odun Owo, Odun omo ni ki odun na je fun gbogbo wa.

Mo fe fi ye nyin wipe, ni te bere kiea Onise bi ko se eniti o ba se dopin. Bi ohun kan yio ba daru, o ni lati koko buru ni ipilese. Lagbara Olodumare, Egbe Afenifere ni yio gba Ijoba ninu ibo ti o mbo yi, Asure tete ko ni oye je, aringbere ni yio mu ori oye dele.

## Advert. No 177

## PRISONS DEPARTMENT, NIGERIA.

TENDER FOR THE SUPPLY OF COTTON SINGLETS

Tenders are invited from local manufactures in Nigeria for the supply of cotton singlets, description as shewn below, to the Federal Government Prisons. durng the the finanical year 1st. April, 1961 to the 31st March, 1962.

(a) "V" Neck Khaki coloured Cotton Vest with short sleeves

| Quantity Required | Size | Round Chest | Length | Length of Sleeve | Length of 'V' vertically from shoulder |
|---|---|---|---|---|---|
| 240 dozen | 1 | 36" | 31" | 4" | 9" |
| 290 dozen | 2 | 38" | 31" | 4" | 9" |
| 100 dozen | 3 | 40" | 32" | 4" | 9" |

(b) Round Neck Sleeveless Khaki coloured Cotton Vest

| Quantity Required | Size | Round Bust | Length |
|---|---|---|---|
| 20 dozen | 1 | 34" | 36" |
| 20 dozen | 2 | 36" | 38" |
| 10 dozen | 3 | 40" | 40" |

2. The Tender should stare the price per dozen delievered to the Prisons Central Store, Lagos and such price should include all charges for parcking handling, and freight.

3. Delivery is to be made within six months from the date the contract is awarded.

4. All tenders should be forwarded in sealed envelopes or parckages, addressed to the Secretary, Federal Tenders Board, Lagos, and should be accompanied by samples, so as to reach this office not later than 9 a.m. 14th February, 1961. The envelopes and/or parckages should be clearly marked *"CONFIDENTIA SINGLETS."*

5. The Board is not bound to accept the lowest or any tender.



## Akiyesi Pataki

**Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!**

(EXTRA STRONG FOR AGED MEN)

SENGOVAN Tablets:- Ję Ajidewe fun awọn agbalagba ati Ilera gẹgẹbi ọmọkunrin.

SENGOVAN. Wa fun Atura ati Alera ni aye ilopo gegebi Ọmoge.

SENGOVAN: Jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni Ilu Okere ni ilẹ Jamani lọwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn Oniṣegun Arẹmọ ti Iwọ orun Jamani, fun arẹ Ara, eni ọjọ ori-Ogoji si Ogọrin ọdun (40 80years).

SENGOVAN: Jẹ ogun ti o ti wa lọjọ pipẹ fun anfani awọn Agbagba Ilu Jamani, ki a to ṣe amuwa rẹ si Ilu Naijira.

Ajẹ bi idan ni ogun yi Irohin ko to Afojuba.

Bere A o ri lọwọ awọn Oniṣegun (Doctors) Naijiria tabi lọwọ alagba wa Messrs HASSAN COMMERCIAL

MEDICINE STORES, 26, BISHOP STREET LAGOS. PHONE 23745.

DIRECTION: 1 to 2 Pills to be taken half an hour before result is wanted try whether 1 only pill is surfficent for your consitution: if so, do not take more pills at one time. SENGOVAN IS FOR YOU.


Printed and Published by ODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, Lagos Phone: 21985. Olotu: E. A. Adeniji 51, Tejuoso Street Suru-Lere YABA

## Awati ni olopa fi Dokita Obi se

EKO.

ILE Ejọ Giga Eko tun sun ẹjọ ti Ijọba pe Dokita Chike Obi siwaju di ọjọ kẹrindilogun oṣu kini ọdun yi.

Ẹjọ ti Ijọba si mba ogbeni Chike Obi ro ni wipe o sọte o si se afojudi si Ijoba nipa iwe kan ti o kọ sodo laipẹ yi. Dokita Chike Obi jẹ eni ọdun mẹkandilogoji.

A sọ fun wa wipe awọn olopa fi ọgbeni Dokita yi ṣe awati, Ọgbeni Williams eniti iṣe agbejoro fun Ijọba fi han ile Ejọ wipe awọn olọpa ti npara ile Dokita Obi lainiye igba lati le fun ni iwe ipejọ, sugbọn wọn ko ri rara.

Ọgbeni Williams tun sọ wipe ti ile Ẹjọ ba le sun ejọ na siwaju fun bi ọsẹ meji tabi mẹta, Ọlọpa yio le ri Dọkita obi lati mu wa si ile ẹjọ. Nigbati Adajọ agba ti ile ẹjọ Eko ati iha gusu kamarun bere lọwọ awọn ọlọpa wipe enia melo ni wọn yio pe gẹgẹbi ẹlẹri ni ọrọ na wọn si dahun wipe ẹlẹri meje ni awọn yio pe.

A fi ye wa wipe Dọkita obi pin awọn iwe kekeke kan laipẹ yi ninu eyiti o ti kọ wipe "Awọn enia" otitọ ti ẹ nilati mọ iwe ti o tẹ yi ni a sọ wipe o fi bu Ijọba, o si ṣori kunkun si i, ni oṣu August ọdun ti o kọja yi, ni o tẹ iwe na jade.

## IDIJE IDIJE IDIJE

A fi eyi kede fun awọn Okawe Irohin jakejado gbogbo awọn ọmọ karọ-O- jire agbaiye pe anfẹ:- Idahun ti o yanju rekete fun awọn ibere wọnyi ki ẹ fi eyiti ṣe ti Bibeli ṣe ti Bibeli ki e si fi eyiti se ti ilu ṣe ti ilu. Enikẹni ti o ba si bori ninu gbogbo ibere yi yio gba Ẹ b u n pọnun kan sile-kan (£1 : 1/-).

IBERE NA NI WỌNYI

1. Ọna wo ni Ọlọrun gba fi ironu rẹ han awọn ọmọ enia.
2. Ọna kansoso wo ni ẹkọ Bibeli fi san ju?
3. Ni Ilu wo ni wọn gbe bi Gomina Ilẹ Naijiria ti o ṣesẹ jẹ si?
4. Ni ọdun wo tabi ọjọ wo ni iwe Irohin Imọlẹ kọkọ jade ni Ilu Eko?
5. Ilu wo ni wọn ti nlu ilu ti ẹnikan si ntumọ rẹ lasiko Ominira ti ọmọ Ọba Alexsandra wa si Eko?
6. Kinni o nfi ilu na wi?
7. Igba wo ni o daju pe Bibeli le pẹ da?
8. Kiniṣe ti awọn ẹlẹṣẹ fi korira Bibeli?
9. kini ohun pataki ti o sẹlẹ ni ọjọ kejidilogbọn oṣu kẹta ọdun 1958?
10. Tani ẹniti e le mu nkan ijinlẹ Ọlọrun wa si ọkan enia?

AKIYESI:— Idahun ibere yi yio pari ni gbigba ni ọjọ kẹrindilogun oṣu Kini ọdun 1961. Kọ idahun rẹ ki o han rekete, ti ẹniti ko ba han a o fa ya ni, ki o si mọ daju wipe ko ni ipa ninu Idije na, ti ẹniti o ba dahun mọwẹwa pe, ti o si gba ni a o tẹ jade ninu iwe Irohin I m ọ l ẹ yi, a o si fi pọnun kan sile kan (£1 : 1/-) Postal Order ranṣẹ si. A ko kọ ọmọde tabi agbalagba. Fi Stampu Toro ranse fun gbigbe pọnun kan sile kan ti o ba jẹ pada tsọ. Ge ibiti Idije yi gbe wa ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stampu Tọrọ rẹ Enikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ ti ko si fi Stampu Tọrọ si ti o ba je owo na a ko ni fi ranse si, a ko si ni f u n ni Stampu rẹ pada.

Orukọ ..............................

Ibugbe ..............................

..............................

Iṣẹ ..............................

Ọjọ Ori ..............................

Fi i d a h u n ibere rẹ yi ranṣẹ si:—

OLOTU IROHIN IMOLE
16 BAMGBOSE STREET LAGOS